*In the Name of Allah, the Most Beneficent, the Most Merciful*

# ÌGBÉSẸ̀ MẸ́SÀÁN TÍ Ó TỌ́ LÁTI GBÉ KÍ A TÓ LÈ ṢÍ MỌ́SÁLÁṢÍ LÁÌ L'ÉWU.

Ìjoba UK ti wipe ìgbà ti o ya julo ti Mosalasi yio di sisi fun irun àjùmọ̀kí ni ilè England ni ojo kerin osu keje (4th July), a o kede ìgbà ti a óò si Mọ́sálásí ni Wales ati Scotland laipe.

A se ètò yìí láti tọ́ àwon alókòóso Mọ́sálásí s'ọ́nà lóríi àsìkò àti ìgbésè tí won yíò lò láti sí Mọ́sálásí fún lílò lá'ìní ewu tàbí ìpalára fún àwon jànmọ́ò àti àwùjo.

**Ìgbésè 1:**
E ní ìpalèmó sílè sájú ìgbà tí e óò sí Mọ́sálásí, ó se pàtàkì kí e yan alábòójútó Covid, e se ìgbélèwòn ewu tí a lè kojú, e gba ìmòràn amòfin, onímò ìlera àti àwon òmòwé lóríi ìgbà tí ó tó àti ìgbésè tó ye láti sí Mọ́sálásí pèlú ìfòkànbalè. E má se kánjú, bí Mọ́sálásí yín bá nílò àsìkò síi kí e lè pèsè lékùúnréré, kò sí làìfí níbè !

**Ìgbésè 2: E ní ìpalèmó ààyè.**
E won àyè tí e níílò fún ònkà túntún àwon olùjósìn. e se òsùwòn àyè gbàgede , kí e ti àwon àyè tí e 'ò bá níílò (bíi àyè àlùwàlá ati ilé ìtò ati ilé ìgbò sè) pa. Bí ó bá rorùn, e se ètò ojúnà àbáwolé yàtò sí àbájáde, kí e sì ní ìgbaradì fún ìmótótó.

**Ìgbésè 3: E ní ìpalèmó oun èló tàbí irin'sé.**
E wá àwon atónà àlèmógiri , èro ìgbowó tí kò ní à nfowó kàn àti òpòlopò oun èlò ìmótótó. E f'enu kò lóríi àwon nkan àdálò (bíi ení tàbí ìté ìkírun, kùránì, ìbomú-ìbonu, atbbl) tí e óò wípé kí olùjósìn kòòkan mú wá.

**Ìgbésè 4: E ní ìpalèmó àyè ìlòsí àti àwon Olùrànlówó.**
E se ìdánilékòó lóríi àwon òfin tuntun, bí a ti nlo oun èlò ìdáàbòbò (PPE), àyèwò COVID bí a ti nwolé, ìlànà ìdarí èrò lórí ìlà, bí a ti nse ìmótótó àyíká, àti àwon òfin tàbí ìlànà òde-ìwòyí, fún àwon òsìsé àti olùrànlówó.

**Ìgbésè 5: E ní ìpalèmó fún àwon alábàágbé.**
E se ètò ìlanilóyè fún àwon jànmóò yín nípa eni tó gbódò kírun ní'lé àti àwon tí yío lánfàní ìrunkíkí nínú Mósálásí.

**Ìgbésè 6:**
E ní ìpalèmó de àsìkò ìrun, e ronú lóríi ètò ìforúkosílè sáájú kí a tó wá sí Mósálásí, ìdarí èrò, àti rírí i dájú pé kò sí ìdíwó kankan lójuònà láti dín ìkesè-b'esè èrò kù, e s'ètò àyèwò rámpé fún Covid lábàáwolé, kí e sì pèsè ìlànà ìrìnà ìdojú ko ibì kan náà.

**Ìgbésè 7: E ní ìpalèmó de ìrun.**
E dín àsìkò tí Mósálásí yíò ma wà ní sísí sílè kù, e ro àwon jànmóò kí wón máa yan Nófílà nílé, e pèsè àlàfo oní Mítà (Metre) méjì sí ra won, e rí dájú pé àlàfo wà láàrín akírun kòòkan sí ra won, e rí dájú pé àsìkò díe ni e fi nse ìbánisòrò / khutbah/ ìrun, kí e sí rí dájú pé e ní òpòlopò sáàfu jànmóò tí àwon akírun fí àyè sílè fún 'ra won.

**Ìgbésè 8: E ní ìpalèmó ètò léyìn ìrun.**
E rí dájú pé e fí ogbòn ìséjú sílè láàrín Ìrun jànmóò kan àti òmíràn, láti fí àyè sílè fún ìmótótó àyè ìkírun, e rán àwon akírun létí pé wón 'ò gbodò fi owó kan elòmíì tàbí bo ara won l'ówó, e lo èro ìgbowó tí kò ní à nfowó kàn tàbí kí e lo èro agbéròyìn kárí ayé tí e bá fé dá owó sí ti Olóhun. E rí dájú pé e ti ilèkùn Mósálásí títí di àsìkò ìrun míràn.

**Ìgbésè 9: E ní ìpalèmó de àwon ìdojúko tàbí ìdàmú.**
Bí enikéni nínú àwon akírun bá kó kòkòrò Covid, e se àkosilè orúko àwon tó wá sí Mósálásí fún àbójútó, ìlànà ìfisùn àti bí a se le wá ìranlówó fún àwon ti 'ò lè wá sí Mósálásí nípa lílò èro agbéròyìn ká'yé.

**Download the full 9-step guide at bit.ly/MosqueReopening**

covid@mcb.org.uk
@muslimcouncil.uk
@muslimcouncil

Training sessions to support you with implementing the above will be starting soon insha'Allah. Please identify your COVID safety officers who should attend the training sessions.

Collated by:
MCB
The Muslim Council of Britain

Help us do more, donate: LaunchGood.com/MCB